# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 569 THURSDAY, APRIL 2, 1964 (2D)

## Ile Wo Pa Ọkọ Iyawo Kan !

OSHOGBO:— Anu ṣe gbogbo enia ilu Oshogbo bi okiki ti kan jakejado arin ilu wipe Sarmọri kan Awosanya ti iṣe ọmọ Ijẹbu-Ode ti o si ngmura silẹ ati ṣe Igbeyawo larin ọṣẹ yi ku lẹṣẹkan bi afẹfẹ nla kan ti wo ogiri ile iwe kan luu mọlẹ pẹlu awọn ọrẹ rẹ marun ni opin ọsẹ ti o kọja yi

Irohin fi ye wa wipe, Ọgbẹni Awosanya pẹlu awọn ẹlẹgbẹ rẹ nti igbẹ ọdẹ ti nwọn lọ ṣe bọ ni afẹfẹ yi ba bẹrẹ ti nwọn si sa wọ ile-iwe-kan ni eti ilẹ pe ti atẹgun nla na ba rọlẹ, ki awọn ma a lọ.

Bi atẹgun yi ti nfẹ pẹlu agbara ni o ba ka awọn panu ori ile-Iwe na ti o si tun ti awọn Ogiri na wo, womuwomu ti osi pa awọn ti o sa si inu Ile-iwe na

Ọjọ keji ni nwọn ṣẹṣẹ fura si pe Ogiri ile-Iwe na wo pa wọn ti nwọn si ti ko wọn lọ si ile-Iwosan.

Irohin miran lati ilu Oshogbo fi ye wa wipe ni adugbo Isalẹ Ọshun ni ile kan ti wolu Baba ati awọn ọmọ rẹ mẹrin mọlẹ ti o si pa wọn lẹṣẹ kan na.

Irohin na tun fi kun pe atẹgun nla yi sọ ọpọlọpọ enia di alaini ti o si tun sọ ọpọlọpọ ile di ahoro ọpọlọpọ enia lo si di alairi ile gbe mọ.

Ara awọn ile-iwe ti atẹgun na wo lulẹ ni ile ikọ ni nisẹ Olukọ ti Aponmi (E T C) ati Bapitist ni ilu Oshogbo

Ki Oluwa rere majẹki a rin ni ọjọ ti ebi npa ọna.

# ARE "YORUBA RONU" WỌLẸ NI IPINLẸ IWỌ-ORUN

IBADAN:— Ni kutukutu owurọ ana ọjọ ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kini oṣu yi ni irohin kan wa wipe Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti pa ni aṣẹ wipe, Ọgbẹni Hubert Ogunde' gbajumọ elere atata ti gbogbo aiye mọ bi ṣugbọn mọ owo ko tun gbọdọ ṣe are rẹ ti o npe ni "Yoruba Ronu" ni gbogbo Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria mọ



Aworan Oke yi ni ti Hubert Ogunde ati awọn Elere rẹ nigbati nwọn nṣere.

Irohin ni alẹ ana, Ṣugbọn nigbati Ofin yi de, ko le ṣe are na mọ.

Ninu awọn ilu diẹ ti Ogunde fẹ gbe ṣe awọn are rẹ na ni, Ile-Ifẹ, Ẹdẹ, Oshogbo, Oyọ, Owo Abẹokuta, Ibadan ati Ogbomọshọ. Ni Ọjọ kejidinlọgbọn Oṣu to kọja yi ni Ogunde fẹ bẹrẹ, are rẹ, ki o si pari are na ni Ọjọ karun Oṣu yi.

A gbọ wipe gbogbo awọn Ọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni nwọn lodi si are "Yoruba Ronu"

Agbọ wipe are na le jẹ ki awọn ara ilu o pa awọn kan ninu awọn oṣelu ni ina "Oro ati ojiji", nwọn si tun lero wipe awọn kan ninu awọn ẹgbẹ oṣelu ni nwọn kọ Ogunde lati maa ṣe are na.

Ọgbẹni Ogunde tiṣe awo rẹkọdu ti o nkọ orin "Yoruba Ronu", a kọ mọ bọya Ijọba yio gba wipe ki awọn tio nta awo na o maṣe tun ta wọn mọ, tabi kini ohun ti Ijọba fẹ ṣe fun awọn ti nwọn ti ra awo rẹkọdu na.

Gẹgẹbi irohin ti o kan wa ni'u ile iṣẹ wa, a gbọ wipe Ijọba sọ wipe, Are "Yoruba Ronu" ti Hubert Ogunde nṣe kakiri ilu ni Ipinlẹ Iwọ Orun jẹ eyi ti "o lodi si ofin Ijọba rere."

Iwe ikede Ijọba na tu ṣe afikun wipe, are "Yoruba Ronu" na jẹ, "are ti o lewu fun Ijọba rere Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria."

Eyi ni ikede ti Ijọba ṣe ni Ibadan ni osan ọjọ Iṣẹgun (Ijẹta) ti iṣe ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu kẹta ọdun yi.

"Gẹgẹbi agbara ofin Ipin 62A akojọpọ Ipin ti awọn aṣofin, a ṣe ofin yi labẹ Gomina ati awọn Igbimọ".

"Asi le lo ofin yi pe, are Ogunde (lodi si ofin) ninu iwe ofin ọdun yi 1964.

Eyi ni lati sọ fun gbogbo enia pe, are Ogunde ti gbogbo enia mọ, eyiti o lewu fun Ijọba rere Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria".

Ikede Ijọba ti o jade na kọ ṣe alaye ohun ti o fa a ti nwọn fi da ọgbẹni Ogunde ni ọwọ kọ lati maa se are "Yoruba Ronu" ni Ipinlẹ na,

Oniwe irohin wa kan fi ye wa wipe, o ti di ogun ọdun loni ti Ọgbẹni Hubert Ogunde ti nṣe are rẹ bọ. Ninu ọdun 1944 lo da are rẹ silẹ.

Ọgbẹni Ogunde jẹ ọmọ Ilu Ijẹbu, o si ti nṣe are orişirişi ni Ilẹ Yoruba eyiti awọn enia maa ngbadun rẹ.

Diẹ ninu awọn are ti Ogunde ma a nṣe ni "Sisi Origarawa, ABD Aiye, Ọba Jaja, Idaji-idaji ati eyi ti o ṣẹṣẹ ṣe nisisiyi "Yoruba Ronu"

Irohin fi ye wa wipe Ọgbẹni Ogunde ti polowo sinu awọn iwe irohin wipe on fẹ ṣe are rẹ yi, "YORUBA RONU" ni awọn ilu mejidinlọgbọn ni ipinlẹ na.

Ni Ale ana, gẹgẹbi ipolowo ti Ogunde ṣe sinu Iwe

## Ile Igbimọ Ipinlẹ Iwọ-Orun Bẹrẹ Ipade

| | |
|---|---|
| N. N. D P | 58 |
| A G | 27 |
| NCNC | 5 |

IBADAN:— Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu ti o kọja yi (Ijẹta) ni Ọlọla, Oloye Joseph Fadahunsi Ọdẹlẹye, Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun ṣe ikede wipe, Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba ati Ile Igbimọ awọn Ọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria yio ṣe Ipade ni Ibadan ni deede agogo mẹsan owuro yi.

Ohunti Ile Igbimọ mejeeji yio ṣe ipade fun ni lati ṣe eto awọn owo ti Ile iṣẹ Minista kọọkan yio na fun ọdun yi ati ọdun ti mbọ (1964-1965).

Oniwe irohin wa kan ran wa leti pe, eyi ni yio jẹ Ijoko Ile Igbimọ Aṣofin na lẹhin ti ẹgbẹ Oṣelu tuntun-Dẹmọ ti wa ni Ipinlẹ na.

Ni ijẹta Ọjọ Iṣẹgun ti iṣe Ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu ti o kọja yi ni eto inawo ti Ijọba ti ṣe silẹ fun ọdun yi ti tan.

Oniwe irohin wa Ejongboro ti o lọ si Ibadan fi ye wa wipe, lati alẹ ana ni awọn ọmọ Ile Igbimọ na ati awọn Ọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti ndẹ si Ibadan fun ipade ti nwọn fẹ ṣe ni owurọ yi.

A gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan yio daba ni owurọ yi nigbati Ile Igbimọ

WO OJU EWE KẸFA

# Ọrọ Ti Ọlọla Azikiwe Fi Ṣi Ipade Ile Igbimọ Asofin

EYI ni Ọrọ ti, Ọlọla Dọkita Nnamdi Azikiwe Olori Apapọ Ijọba Naijiria fi ṣi Ipade Ile Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria ni ọjọ Ọjọ Ru, ti iṣe Ọjọ kejila oṣu kẹta Ọdun yi, nigbati Ọlọla na nba Apapọ Ijoko awọn Agba Oṣelu sọrọ.



**Ọlọla Nnamdi Azikiwe**
OLORI APAPỌ IJỌBA NAIJIRIA

"A.o ki alaga, gbogbo ẹnyin alagba ati gbogbo ẹnyin aṣoju ile igbimọ asofin ilẹ yi

Ohun iyi nla ni o jẹ fun mi lati ba nyin sọrọ fun ipade ti inawo wa kini ti ọdun yi lẹhin igbati eto ise ijọba wa ti yi pada kuro lọwọ ijọba ti ilẹ Gẹesi lati osu kẹwa ọdun ti o kọja yi

Fun idi eyi ngo yin iṣẹ aseyọri ti ijọba mi se nipa dida ipinlẹ ti agbede meji ilẹ Mid—West silẹ, nipari osu ti o kọja yi.

Ijọba mi yio se agbara lati ma wa ọna ifọwọsowọpọ ti igbimọ gbogbo ilẹ Afrika ti se sile. A i eyi ti o ti fi han pe a ko ni yọju si eto orilẹ ede m n ti nwọn ko ba pe wasi.

Awa yio ma se orisirisi atunselarin awọn ilẹ Afrika ti o ba nja larin ara wọn lati le mu alafia sarin ilẹ wa. Ijọba ilẹ Naijiria yio se ọna ti ao fi awọn ọmọ ilẹ Afrika wọ inu igbimọ ilẹ aiye ti yio le fa itesiwaju fun ilẹ wa".

Fun idagbasoke ilẹ wa, Ọlọla Azikiwe sọpe orisirisi iṣẹ ilọsiwaju ni ijọba on yio se fun gbogbo enia ilẹ na lati ilera O tun fi han pe Ijọba on yio fi kun awọn Ọlọpa ki nwọn le kari gbogbo ilu, lati le fun gbogbo enia ni alafia O tun sọ pe Ijọba on gbero lati le sagbara ati le sọ awọn ọmọ ogun ilẹ wa di alagbara ati pe nwọn yio kọ ile ẹkọ nla ti awọn ọmọ ogun miran lọjọ aipẹ.

O tun fi ye awọn aṣoju wipe iṣẹ nla yio bẹrẹ nipa kikọ ile iṣẹ nla kan nibiti wọn yio ti ma rọ a w ọ n ohun ija fun awọn ọm ogun ilẹ wa.

O fi han pe, ijọba ti ṣe tan lati le ra awọn ọkọ oju omi miran kun e y i ti a ni lati le fa owo nla fu ilẹ wa

O tun fi han pe, ijọba yio ṣe eto lati le ra ọko' ofurufu nla miran lati le ma fi ko ero lọ si ilu oyinb ati awọn ilu miran, lai i ida duro.

O tun sọ wipe Ijọba on yio ṣe agbara ati le kọ ọpọ lọpọ ile ifiweranṣe si gbogbo ilu ati lati le ṣe awọn gbogbo iṣẹ miran ti o ye wọn.

O fi han pe ijọba on y i o kọ ile iṣe Telifiṣọn kan si ilu Ikorodu ti yio lagbara ati le fun gbogbo ilẹ wa i irohin lati ilu Okere.

Otun sọ pe, awọn yio ṣe afikun nipa iṣẹ awọn ina ẹletiriki wa ti ko fi ni si iyọnu nigba kankan.

Ọlọla Azikwe sọ wipe Ijọba on yio fọwọsowọpọ lati le siṣẹ pelu Ijọba Ipinlẹ kọkan.

Nipa oro awọn Agbe ati ohun ọgbin Ọlọla Azikiwe fihan pe Ijọba on ti ṣe tan lati ran awọn agbẹ lọwọ i nwọn e pese ohun ti yio ṣe ilẹ wa ni anfani

O tun ihan pe, pelu ifọwọsowọ ọ awọn Ijọba Ipinlẹ kọọk n ni ilẹ Naijiria; awọn y o se agbara lati le ṣe iranlọwọ fun awọn ọmọ ile iwe ti ko ri iṣẹ ṣe.

O tun sọ pe Ijọba yio tun awọn titi nla nla mẹrinlelogun ṣe larin ilẹ wa lati mu ohun ọpọlọpọ jamba kuro larin ilẹ wa.

Awọn alagba lati ṣe iṣẹ wọn gẹgẹbi oti ṣe ye wọn laiṣe ye meji

O ṣe ileri pe, gẹgẹbi igbimọ gbogbo agbaye ti ṣe tan lati tun ilu Eko ṣe ki o le ba oju mu, ijọba on yio ṣe agbara lati le fi owo le lẹ fun iṣẹ na.

O sọ wipe ijọba on yio gbe ofin kan kalẹ lori awọn Oṣiṣẹ ilera (Nurses) lori iṣẹ wọn ati ofin miran lori atile gbogun ti arun iba panjupanju.

O tun fi han mi pe, ijọba on ti nkọ ile iwosan marun sarin ilu Eko lati le mojuto orisirisi aisan ti o wa larin ilu yi

Nipa are idaraya ati ti awọn ti ngba bọlu, Ọlọla Azikwe sọ pe ijọba on ṣetan lati ṣe iranlọwọ.

Awọn yio fi owo nla sile lati le k awọn ọdọmọkunrin ni are ti o ba ode oni mu ki a le ba awọn ilu miran dọgba

O fihan pe orisirisi ofin ni yio wa siwaju wọn fun atunṣe ki o le ba Ijọba alailọba wa mu.

Ni pari ọrọ rẹ o sọ fun gbogbo awọn aṣoju ati awọn Alagba lati ṣe iṣẹ wọn gẹgẹbi o ti ṣe ye wọn lai ṣe iye-meji.

AH! REMEMBER THAT

**The Social Dandies**

*PRESENTS*

**An Eid-Ul-Kabir Dance**

AT

**FORSTER CENTENARY HALL**

22, Odunlami Street, Lagos. On Sunday 26th April 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till down

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, seize this opportunity and come and listen to the latest heats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E., Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be here in time to avoid rushing.

**Tickets: 4/- Flat**

Tickets now on sale at 3, Olushi Street Lago 16, Bamgbose Street, Irohin Imọlẹ Office Wẹnimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Mett

# Ọwọ Ọlọpa Tẹ Alfa Yesufu Ti Nṣe Baranda

EKO:- Ha ! se gbogbo ero ti o pejọ sile ẹjọ kan ni ilu Eko ni ipari ọsẹ ti o kọja yi bi awọn Ọlọpa nti nfi han ile ẹjọ wipe, Alfa Yesufu Omi Oke ti fi ọgbọn alumọkọrọyin gba owo ti o le ni ẹgbẹrun pọnun lọwọ awọn onisowo mẹta.

Bi Ọlọpa nti fi ẹsun na kan Alfa ọdaran yi nse ni o duro sigidi sinu apoti ti o si wọle bi ẹran.

Awọn ọlọpa fi han ile ẹjọ wipe Alufa Yesufu pe ara rẹ ni Onibarada ti ti nta iwe ẹkọ ti ẹsin Islamu pẹlu orisirisi tira ati Alukurani ati pe on jẹ asoju pataki fun isowo kan ti ilu Larubawa ti wọn npe ni "Taji Company Limited".

Nwọn tun fi kun wipe bi Alufa yi ti polowo ara rẹ kakiri ni o ba de ọdọ enia mẹta yi ni ọjọ kerindinlọgbọn osu kejila ọdun 1962.

Awọn ọlọpa sọ wipe alufa ti de ọdọ Iyaafin Ayisatu Abakẹ pẹlu Ọgbẹni Karimu Talibi ati Alfa Lawani ti osi bẹrẹ si se alaye ise ti on se ni dajowo ti ole ni ẹgbẹrin pọnun jọ (£800; 17:7d) ti osi gba lọ ti o si se ileri fun nwọn wipe on yio fi orisirisi tira pẹlu Tẹsuba alarabara ati Alukurani ranse si wọn n ẹdiwo

Awọn ọlọpa tun fi han wipe lẹhin ọpọlọpọ osu ti Alufa Yesutu ti gba owo yi tan, ni awọn ti o fun ni owo ko gburo rẹ mọ ti wọn ko u lẹ ri ọja ti nwọn bẹ lati ra fun wọn.

Bi awọn Ọlọpa fi pari ẹsun wọn ni w n bere lọwọ ọdaran Alufa na bi ọba jẹbi ẹsu n na Alufa Yesufu dahun wipe on ko jẹbi ẹsun ti wọn fi kan on.

Ni Adajọ kotu na ba sun ọjọ gbogbo ẹjọ na si ọjọ kerinla osu kerin,

Bi nwọn bati se ejọ na si ẹ o tun ma gbọ o.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 20 - Feb 18) Ọjọ oni dara fun ọ lati lọ ri olufẹ rẹ. Maṣe gbagbe lati ṣe awọn ohun ti yio wulo fun ọ.

PISCES ( Feb 19 - March 20) Mu gbogbo iwa ibajẹ kuro ni ọkan rẹ ma ṣe jẹki o han si awọn alabagbe rẹ.

ARIES (March 21 - April 19) Ore nla kan yio de ba ọ, fi ifarabalẹ ṣe gbogbo awọn iṣẹ rẹ. Maṣe ṣe iye meji.

TAURUS (April - May 20) Arẹ ara pẹlu aini ifọkanbalẹ yio de bajọ. Mura lati doju kọ gbogbo iṣoro ti o wa niwaju rẹ.

GEMINI (May 21 - June 20) Iwọ yio ṣe orire nla ọdọ olufa rẹ ati gbogbo awọn ojulumọ rẹ ti o yi ọ ka.

CANCER (June21-July20) Irora ati wahala iṣẹ rẹ yio de ba ọ mura lati gbọ imọran ti nwọn ba ba ọ da.

LEO (July21-Aug.20) Arọ yi kun fun ọgbọn lati ore fun ọ, se akikanju nipa gbogbo ọna rẹ ki o le dara fun ọ.

VIRGO (Aug. 21-Sept.20) Ọpọlọpọ o b u n rere ati iyalẹnu ni Iwọ yio ri loni Iwọ yio tulẹ se alabapade awọn alanu ti yio se ọ lore.

LIBRA (Sept.21-Oct.22) Maṣe ba ẹnikan se ariyanjiyan ọrọ, ki Ijamba ma ba de ba ọ. Ba ololufẹ se adehun ti o dara.

SCORPIO (Oct 23-Nov 21) Ọ kan yio de ba ọ lojiji ti yio le mu ọ se gbogbo awọ iṣẹ rẹ.

SAGITTARIUS(Nov 22-Dec 21 Daru dupọ yio ṣelẹ lẹnu iṣẹ rẹ, maṣe ba wọn da si ọr ti kọ kan ọ.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 19) Maṣe ronu pupọ nipa awọn iṣoro ti ode ba ọ. Ṣugbọn ki o fi ọkan balẹ bogbo rẹ yio yọri si rere.


## Akiyesi Pataki

A nfẹ Aṣoju ni awọn ilu wọnyi, Ọtta Abẹokuta, Ibadan, Iludun, Ololo, Agbọwa,-Iko si Ikorodu, Ọyọ, Awẹ, Ilesha, Ẹde, Ikirun, Iwo Shaki Iṣẹyin, Tede, Oke Amu, Iganna, Omu-Aran Ilorin Ajaṣẹ-Ipo, Iffọ Abalabi, Idọgọ.

Akọwe si
Circulation Manager.
16, Gbamgbose Street,
Lagos.

## EGBOGI JẸDIJẸDI

BERE FUN EGBOGI



**"CYCLOVEN"**

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ o si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ.. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma polowo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe bọya bi wọn ba lọ si ilẹ Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana. Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna ṣelu lojojumọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ jade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egbogi "GYCLOVFN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ a ki o si danwo orişi meta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹioprw napata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogid- ıaa igbero ilu Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:—

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Fai)

## BI O BA NI Iwe—Titẹ

FUN

**Bilo nibi iṣẹ rẹ tabi orişirişi Iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ ẸRỌ—ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgbose Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITEWE WA NHAN OWO ỌKU NI A SI NBGA

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Danwa wo lẹẹkanṣoṣo ki o si ri iyato*

# IROHIN IMỌLE

MỌLE ORI AIYE, TẸNI GBOGBO LA WA

No. 568 THURSDAY APRIL 2, 1964 (2D)


## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lẹhinti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti awọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi ye gbogbo enia ki o ye wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imọle Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni ongbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ, Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati ọdun n... (19..) sẹhin.

Ao ṣe ifilọ yi lori Ra... fun gbogbo enia lati gbọ, ṣugbọn ẹniti o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nọmba

16, BAMGBOṢE STREET,
PHONE 21985, LAGOS

# Egungun Ti O Na Ọlopa Ni Ana Sare Fara Han Adajọ

IJẸBU-ODE:- Gbogbo ero ti o pẹjọ si ile ẹjọ kekere kan ni Ijẹbu-Ode ni o rẹrin arin takiti ti nwọn si sọ pe a se enia ni "ara Ọrun" ti ngbe Egungun bi awon ọlọpa ti nka ẹsun si ọdaran kan, Adekanmi Alamoran lọrun ni ọjọ iṣẹgun ti ise ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu ti o kọja yi.

Awọn ọlọpa sọ pe Alamọran ẹni ọdun marudinladọta (45) jẹ ọkan ninu awọn Olori Egungun ti o na Ọlọpa Ijọba ibilẹ kan, Ọgbẹni Ọbatolu ni ana sare ti o si tun gbagbe bata rẹ si lẹ ni ọsẹ meji sẹhin.

Awọn ọlọpa tun fi kun wipe ninu oṣu kẹta ọdun yi ni Ọgbẹni Raifu Ọbatolu ti iṣe ọlọpa Ijọba ibilẹ mura ti o si nlọ si ile ololufẹ rẹ ti o si pade awọn egungun yi ti nwọn kesi pe ki o bọ bata ẹsẹ rẹ ki o si tun ṣi fila rẹ silẹ.

Ṣugbọn bi Ọgbẹni Obatolu ti kọ lati ṣe !ẹ, ni awọn Egungun yi ba bẹrẹsi fi ẹgba wọn dara si lara, ti o tun fi ọgbọn bọ ẹwu rẹ lọrun ti o wa fi ẹsẹ fẹ ẹ nigbati atori dun daada.

A gbọ wipe bi awọn Ọlọpa ti ka ẹsun yi si Alamọran lati tan ni o ba sọpe on ko jẹbi ẹsun ti awọn Ọlọpa mu on fun.

Adajọ wa tun sun ọjọ gbigbọ ẹjọ na di ọjọ kẹjọ oṣu kẹfa ọdun yi.

Nwọn ni ki Alamọran lọ wa ẹniti yio duro fun un lori ọgọrun pọnun (£100) ati onigbọwọ lori iyekanna.

Bi nwọn ba ti ṣe ẹjọ na si ẹo ma a gbọ o.


make it a successful
SEASON
with MERCEDES-BENZ
TRUCKS

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.


### LATI OJU EWE KINI

na ba nṣe ipade wipe ki Oloye S. L. Akintọla Alakoso Ijọba ki o tu Ile Igbimọ na ka ki awọn enia Ipinlẹ na o le ni anfani lati dibo fun ẹgbẹ oṣelu ti nwọn ba nfẹ.

Awọn ọmọ ile Igbimọ na kọkọ se ipade kan ni alẹ ana lati lẹ mọ ohun ti nwọn sọrọ le lori ninu ile Igbimọ na ni owurọ yi.

Agbọ wipe ẹgbẹ Afẹnifere ati ẹgbẹ Alakukọ ni yio jijọ ma a se pọ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria nisisiyi.

Ṣugbọn Agbọrọsọ awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifere kan sọ wipe, ajọsepọ awọn ọmọ ẹgbẹ mejeji na ko ni yẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni kan bi ko se titi de gbogbo igun mẹrẹrin Naijiria,

Oniwe irohin wa kan fi ye wa pe, Owo ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria yio na to ẹgba a Ọkẹ pọnun (£40,000,000) ninu Ọdun yi ati Ọdun ti abọ.

Bi ipade Ile Igbimọ na ba ti nlọ ẹo maa gbọ ninu iwe Irohin wa c.


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbọṣẹ Street, Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M.S.Grammar School) P. O. Box Bariga (2/4/64)